| **1.** | **Asa: Eko-Ile** | **1. Oriki ati apeere eko-ile. Awon iwa omoluwabi. Awon iwa to lodi si iwa omoluwabi.** |
|---|---|---|
| **2.** | **Litireso: Kika iwe ere onise** | **Koko Oro, Ahunpo itan, ibudo itan, eda itan, ati ifiwaweda. Ilo ede ati ijeyo asa. Amuye ati aleebu.** |
| **3.** | **Awon iro ede Yoruba.** | **1. Iro konsonanti**<br>**2. Iro faweli**<br>**3. Iro ohun** |
| **4.** | **Asa: Ounje ile Yoruba.** | **Itumo ati Pataki ounje. Apeere ounje ati bi a se n pese won. Isori ounje. Itoju ounje,** |
| **5.** | **Ede: Silebu ede yoruba** | **Itumo pelu apeere silebu. Ihun silebu. Oro eleyo silebu ati oro olopo silebu.** |
| **6.** | **Ihun oro** | **Itumo ati orisi mofiimu. Afomo ibere ati afomo aarin. Siseda oro-oruko.** |
| **7.** | **Asa: Ise abinibi** | **Itumo ati orisi ise abinibi. Ohun elo ise abinibi. Ikose ati gbigba iyonda lenu ise.** |
| **8.** | **Asa: Igbeyawo nile Yoruba.** | **Itumo ati orisi igbeyawo. Igbeyawo ni liana ibile. Awon igbese ati ohun elo igbeyawo ibile.** |
| **9.** | **Owe ati akanlo ede** | **Itumo ati orisi owe ati akanlo ede. Iwulo ati ilo owe ati akanlo ede.** |

**ÒṢẸ̀ KÌN-ÍN-NÍ - WEEK 1**

**Eko-Ile**

Eyi ni eko iwa omoluwabi ti awon obi fi maa n ko awon omo won. Iru eko bee maa n ran omo lowo ni ojo iwaju.

Apeere eko ile ni:

1. Itoju ara:
   a. oju bibo
   b. enu fifo,
   c. iwe wiwe
   d. aso fifo
   e. ara pipa
2. Itoju ile ati ayika eni
   a. Ile-gbigba
   b. Jiju oko ayika ile
   c. Titun ibusun eni se
   d. Fifo abo ti a fi jeun
3. Itoju ounje
   a. Eko nipa bi a ti n pese orisiirisii ounje bii iyan, amala, gbegiri, eko, asaro, adalu, ojojo, akara, moin-moin abbl
4. Ìtọ́jú àlejò
   a. Ọmọ gbọdọ mọ bi a ti I toju alejo. Bi apeere ohun akoko ti a gbodo se bi a ban i alejo ni ki a gbe ijokoo fun un ki a sib u omi fun un mu.

# ASSIGNMENT

Daruko eniyan marun-un ti won letoo lati ko omo ni eko-ile.

1. ……………………………………………………………………
2. ……………………………………………………………………
3. …………………………………………………………………….
4. ……………………………………………………………………..
5. ……………………………………………………………………..

# Iwa Omoluwabi

Eyi ni awon iwa ti o je itewogba laarin awujo. Ki a to le pe eniyan ni omoluwabi iru eni bee gbodo ni iwa rere, eni ti kii se ole, eni ti kii jale, eni ti kii soro eni leyin ati bee bee lo.

**Apeere iwa Omoluwabi**

1. Iwa ikini
2. Iteriba
3. Irele
4. Igboran
5. Ife omonikeji
6. Iforiti
7. Ipamora abbl.

**PATAKI IWA OMOLUWABI**

1. O n so eniyan di eni giga
2. O n fi okan eni bale
3. O n mu ki irepo wa lawujo.
4. O n mu ki idagbasoke wa laarin awujo
5. O n mu ki alaafia joba laarin awon eniyan

Iwa to lodi si iwa omoluwabi

Janduku, Aigboran, Igberaga, Ojukokoro, Ole jija, imele sise abbl.

## ASSIGNMENT

1. Ki ni ibowofagba? ______________________________________________
2. Toka si idi marun-un ti o fi ye ki a bowo fagba.
   a. ________________________________________________________
   b. ________________________________________________________
   c. ________________________________________________________
   d. ________________________________________________________
   e. ________________________________________________________

# OSE KEJI (WEEK 2)

## ATUPALE IWE <u>EEGUN ALARE</u>

**1. Itan ni Soki**

Oje Larinnaka ri i pe ere idan pipa ko wopo ni apa ibikan, o si pinnu ninu okan re lati lo sere ni adugbo yii boya ohun le ri owo kojo. Sugbon ki o to lo, o pe ore re ti oruko re n je Dasofunjo o si salaye ipinnu re fun un. Dasofunjo ni oun ko ni le tele e lo nitori idiwo ile po fun ohun.

Akoko yii ni iyawo Oje Larinnaka ti oruko re n je Iyadunnni, loyun sinu. Dasofunjo ro ore re ki o ma gbagbe ile, ki o si ranti pe iyawo re loyun sinu. Oje Larinnaka dupe lowo re, o ni bi ohun bat i ri ibi jokoo no oun yoo wa mu iyawo oun. O ro o ki o ba oun toju iyawo oun ti oun fi sile.Dasofunjo fi da ore re loju pe oun yoo gbiyanju agbara oun lati ri i pe oun ran iyawo ore oun lowo. Ki won to pinya Dasofunjo fun ore re ni nnkan amusagbara die, won si ki ara won pe o digba o se.

Ajo ko ri bi Ojelarinnaka ṣe ro. Won ko gburoo re titi iyawo re fi bi omo. Daṣofunjo ati awon molebi Ojelarinnaka so omo naa ni Ojelade. Nigba ti won wo akosejaye re won ri i pe ise eleegun ni iṣe aṣela re.

Nigba ti Ojelade pe omo odun mesan_an ati oṣu meje ni Iyadunnni pinnu lati wa oko re lo. Daṣofunjo ro o ki o ma lo sugbon o fi gbigbo ṣe alaigbo. O fi odidi odun kan wa oko re sugbon ko ri i. Nigba ti o pada dele won fi Ojelade si odo Daṣofunjo, ore baba re lati ko ni iṣe eleegun. Leyin odun meta o gba iyonda won si se ayeye igbayonda lenu ise fun un.

Bi o ṣe pari ayeye yii Dasofunjo fa omobinrinre, Anṣeetu le Ojelade lowo ki o fi se aya. Ojelade pinnu lati ṣe ere lo si ilu okeere, Dasofunjo ro o ki o ma lo. Sugbon o ni erin ki i fon ki omo re fon.Okiki Ojelade bere si kan kaakiri. Eyi mu ki baale ilu kan ranse si Ojelade lati wa ṣere fun oun. Bi o se de abule yii ni o lo si ile agba eleegun kan ti o wan i abule naa lati lo ki i. Ojelade ko mo pe baba oun ni. Bi baba yi se ri iyawo Ojelade o bere si da a laamu nitori ewa re pe oun fe fi se aya ni. Ojelade je ki o ye baba yii pe aya oun ni.

Ojelade di orisirisi nnkan ni ojo yii. Wọn wo kẹrẹ̀ẹ́, o ta okiti, o di oyinbo, olopaa, ekun ati ojola. Nigba ti o di ojola ko le yi pada di eniyan mọ. Awon elere re fe fi obe la ojola naa ki won si gbe oga won jade. Ibi ti won ti fe se eyi ni ojola ti bere si fi eṣa korin ti o si n ki ara re ati baba re. Bayi ni baba agba eleegun yii gbo oruko ara re asiko yii lo mop e omo oun ni Ojelade. Jebete gbomo le e lowo. O sare lo si ile lati lo mu ero ti o si tu omo re sile. Bayi ni gbogbo won gbera ti won si gba ilu won lo.

**ASSIGNMENT**

1. Ta ni olu eda itan iwe Eegun Alare?
2. Ki ni oruko iyawo Oje Larinnaka?
3. Ki ni o fa a ti Oje Larinnaka se pinnu lati lo sere ni ilu miiran?
4. Ipo wo ni iyawo Oje Larinnaka wan i asiko yii?
5. Kin ni o fat i dasofunjo ko fi lo?

## OSE KEJI
## AWON EDA ITAN IWE EEGUN ALARE

1. Oje Larinnaka
   Oun ni baba Ojelade.
   Oruko iyawo re ni Iyadunnni.
   Oruko ore re ni Dasofunjo.
   Ise ti o yan laayo ni eegun alare ti a tun mo si pidanpidan
   O kuro ni ilu re lati lo pidan ni ilu odikeji.
2. Dasofunjo
   Ore Oje Larinnaka ni
   Eegun pidanpidan ni oun naa.
   Oun ni Oje Larinnaka fi iyawo re, Iyadunnni le lowo nigba ti o fe rin irin ajo.
   O fun Oje Larinnaka ni nnka amusagbara nigba ti o n mura irin-ajo.odo re ni Ojelade ti ko ise eleegun.
3. Iyadunnni
   Oun ni iyawo Oje Larinnaka.
   O ni oyun sinu nigba ti oko re n mura irin-ajo.
   Oruko omo re ni Ojerinde.

## ASSIGNMENT

Salaye ohun ti o mo nipa iwe Eegun Alare.

## OSE KETA (WEEK 3)

## IRO KONSONANTI EDE YORUBA

Iro konsonanti ni iro ti a pe nigba ti idiwo wa fun eemi ni ibikan ni opona ajemohun. Awon konsonanti ede Yoruba ni: b d f g gb h j k l m n p r s s t w y

### ONA TI A N GBA SAPEJUWE IRO KONSONANTI

1. Ibi isenupe
2. Ona isenupe
3. Ipo tan-an-na

a. Ibi isenipe – place of articulation
   - i. Afejietepe: ***b, m***
   - ii. Afeyinfetepe: ***f***
   - iii. Aferigipe: ***t, d, s, n, r, l***
   - iv. Afajaferigipe: ***j, s***
   - v. Afajape: ***y***
   - vi. Afafasepe: ***k, gb***
   - vii. Afafasefetepe: ***p, gb, w***
   - viii. ***Afitan-an-nape: h***

**b. Ona Isenupe – Manner of Articulation**
   - i. Asenupe: ***b, t, d, k, g, p, gb***
   - ii. Afunnupe: ***f, s, s, h***
   - iii. Asesi***: j***
   - iv. Aranmu: ***m, n***
   - v. Arehon***: r***
   - vi. Afegbe-enu-pe***: l***
   - vii. Aseesetan***: y,w***

## ASSIGNMENT

Se apejuwe ibi isenupe awon iro konsonananti wonyi:

1. /m/________________________________________
2. /k/________________________________________
3. /t/________________________________________
4. /gb/________________________________________
5. /y/________________________________________

# ỌSẸ KẸTA

# APEJUWE IRO FAWELI

**Iro Faweli:** Eyi ni iro ti a pe nigba ti ko si idiwo fun eemi ni ibikan ni opona ajemohun. Apapo faweli ti o wa ninu ede Yoruba je mejila.

**2.7. Orisi Faweli**

a. **Faweli Airanmupe:** Eyi ni faweli ti a pe nigba ti afase di kaa imu ti eemi si gba enu jade. Faweli airanmupe meje lo wa ninu ede Yoruba.
Apeere: ***a, e, e, i, o, o, u.***

b. **Faweli Aranmupe:** Eyi ni faweli ti a pe nigba ti afase wa sile ti eemi si gba imu ati enu jade. Faweli aranmupe marun-un lo wa ninu ede Yoruba.
Apeere: an, en, in, on.
Eemi gba imu nikan jade nigba ti a pe ***'un'***

**a. Giga ahon si aja enu (height of the tongue)**
- i. Oke : Ahanupe:- ***i, u, in, un***
- ii. Ebake: Ahanudiepe:- ***e, o***
- iii. Ebado: Ayanudiepe:- ***e, o, en, on***
- iv. Odo: Ayanupe:- ***a, an***

**b. Abala ahon ti a l*o: Parts of the tongue***
- ***i.*** Iwaju ahon*:-I, e, e, in, en*
- ***ii.*** Aarin ahon*:= a, an*
- ***iii.*** Eyin ahon*:- u, o, o, un, on*

**c. Ipo ete: *Position of the lips***
- ***i.*** Perese*: I, e, e, a, ain, en, an*
- ***ii.*** Roboto*: u, o, o, un, on*

**d. Ipo afase*:- Position of the soft palate***
- ***i.*** Airanmupe*:- a e e i o o u*
- ***ii.*** Aranmupe*:- an en in on un*

**e. Ipo Tan-an-na*:- Position of the glottis.***
*Gbogbo faweli Yoruba ni akunyun.*

***ASSINGMENT***

Ya ate faweli ede Yoruba sile.

**OSE KERIN (WEEK 4)**

**Asa Ounje Ile Yoruba.**

Ounje ni ohun ti eniyan je tabi mu lati fun eniyan ni okun ati agbara. Ounje ni ore awo. Bi eniyan ko ba jeun iru eni bee ko le pe dagbere faye.

Pataki Ounje

1. Ounje maa n mu eniyan dagba
2. Ounje a maa pa ebi lara eni.
3. Ouje maa n fun eniyan ni okun ati agbara.
4. Ounje a maa dena aisan ati arun lara eniyan.
5. Ounje maa n mu ara dan a si maa mu ara jolo.

Orisi Ounje

1. Isu: iyan, amala, asaro, dundu, isu sise, isu sisun,.
2. Ege / gbaguuda / paki: lafun, fuufu, iyan ege, gari abbl
3. Agbado: ogi, eko jije, eko mimu, abari, sapala, adalu, abbl
4. Ewa: monu, moin-moin, akara, ewa riro, ekuru, abbl
5. Ogede Agbagba: amala ogede, dodo, ipekere, booli, oti abbl

**Pipese Iyan**

Be isu mo tonitoni
Sin in nu daradara
Gbe omi ka ina
Da isu si inu re
Ko ina mo o fun ogbon iseju.
Da a sinu odo
Fi omo odo gun un kunna.
Fi omi die si i
Ko o sinu abo.

## ASSIGNMENT

Sapejuwe bi a se n pese iyan.

**ISORI OUNJE:** A le pin ounje si isori marun-un

1. Ounje Afaralokun (Charbohydrate): Eyi ni ounje ti o n fun ara wan i okun ati agbara. Apeere ounje afaralokun ni iyan, asaro, eba, egbo, ikokore, amala, eko, isu sise, fufu, isu sisun, ati bee bee lo.

2. Ounje Asemiro (Protain): Eyi ni ounje ti o maa n so emi eni ro. Apeere ounje asemiro ni eyin, eja, eran, ede, ewa, moin-moin, akara, adalu, abari, ekuru ati bee bee lo/
3. Ounje Amardan ati Amarajolo (Vitamin): apeere ounje amarajolo ni awon eso bii orombo, igba, gurofa, ibepe, ope oyinbo, agbalumo ati awon ewebe bii gbure, sokoyokoto, gbagba, ewuto, tete, ooyo, ila, tomato, alubosa ato bee bee lo.
4. Ounje Oloraa (Fat and oil): Eyi ni ounje ti a le ri ora lara won. Apeere iru ounje bee ni ora eran, ororo, epo pupa, eran elede, ati bee bee lo.
5. Ounje Oniyo (Mineral salt): Eyi ni awon ounje ti o ni iyo nlara. Bi apeere iyo, anamo, ogede wewe, ireke, suga ati bee bee lo.

## ITOJU OUNJE AJESEKU

1. Ounje didin.
2. Ounje yiyan.
3. Ounje sisun
4. Sisa ounje ni oorun.
5. Gbigbe ounje ka ina loorekoore
6. Ounje sise

## ASSIGNMENT

Salaye ona meta ti a le gba toju ounje ajeseku.

1. ___________________________________
2. ___________________________________
3. ___________________________________

.

## OSE KARUN (WEEK 5)

Silebu ni ege oro ti o kere julo ti a le pe jade lenu leekan soso laisi idiwo Isemii. Iye ibi ti ohun ba ti jeyo ninu oro kan ni iye silebu oro naa. Orisii silebu lo wa:

**ÀWỌN OHUB TÓ ṢE KÓKÓ NÍPA SÍLÉBÙ**

1. Kọ́ńsónáńtì kì í parí sílébù èdè Yorùbá.
2. Iye ami ohun ti oro kan ba ni ni iye silebu ti o wa ninu oro bee.
3. Fáwẹ́lì méjì kò lé wà nínú sílébù kan.

**Ọ̀rọ̀ Ẹlẹ́yọ àti Ọlọ́pọ̀ Sílébù**

1. **Ọro eléyọ sílébù**: Ẹ̀yí ni ọ̀rọ̀ tí kò ní ju ẹyọ sílébù kan lọ nínú ìhun rẹ̀.

a. Eyi le je eyo faweli kan – a e ẹ i o ọ u

Bi apeere: Ṭópẹ́ **a** jẹ iṣu. Ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yọ sílébù ni **a** nínú gbólóhùn náà.

b. O si tun le je faweli aranmupe – an en in on un.

Bí àpẹẹrẹ: Ìdòwú nà **án** . Ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yọ sílébù ni **an** nínú gbólóhùn òkè yìí.

c. Ó lè jẹ́ końsónáńtì aránmú aṣesílébù m tàbí n. Bí àpẹẹrẹ

Adé ń gbá bọ́ọ̀lù. Ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yọ sílébù ni **n** nínú gbólóhùn òkè yìí.

d. **O** tun le je akanpo kosonanti ati faweli. Bí àpẹẹrẹ:

Gun, jin, gba, ra, pa, je,

2. **Ọ̀rọ̀ ọlópọ̀ sílébù** : Eyí ni ọ̀rọ̀ tí ó ní sílébù méjì tàbí jù beẹ̀ lọ nínú ìhun rẹ. Bí àpẹẹrẹ :

| Oro(Words) | Ege(Division) | Iye silebu(Number) |
|---|---|---|
| Nnkan | N-n-kan | Silebu meta |
| Ekunrere | E-kun-re-re | Silebu merin |
| Ogedengbe | O-ge-de-n-gbe | Silebu marun-un |
| Konsonanti | Ko-n-so-na-n-ti | Silebu mefa |

**ASSIGNMENT**

Pin awon oro yii si silebu:

(a) Owo ____________

(b) Ati______________

(c) Iwo_____________

(d) Ohun_____________

(e) Igun_____________

## Ìhun Sílébù Èdè Yorùba

A lè pín Yorùbá sí ọ̀nà mẹ́ta.

1. Ògédé fáwẹ́lì (F)
2. Àpapọ̀ kọ́ńsónáńtì àti fáwẹ́lì (KF)
3. Kọ́ńsónáńtì aránmúpè aṣesílébù (N)

1. Ògédé fáwẹ́lì (F)

   Àlágbẹ̀dẹ - a-lá-gbẹ̀-dẹ - f-kf-kf-kf

   Aláǹgbá –a-lá-ǹ-gbá = f-kf-N-kf

   Àlàáfíà – à-là-á-fí-à = f-kf-f-kf-f

**OSE KARUN-UN**

**ASSIGNMENT**

Ko oro olopo silebu mewaa sile ki o si daruko iye silebu to wa ninu okookan won.

1. ______________________
2. ______________________
3. ______________________
4. _______________________
5. _______________________
6. _______________________
7. _______________________
8. ________________________
9. ________________________
10. _______________________

**OSE KEFA (WEEK 6)**

# Ìṣẹ̀dá Ọ̀rọ̀

**MOFFIMU**

Eyi ni ege oro ti o kere julo ti o sin i itumo. Iru itumo bee le je onitumo girama tabi itumo adani.

Orisii Mofiimu: A le pin mofiimu ni ede Yoruba si ona meji:

1. Mofiimu Afarahe: eyi ni mofiimu ti ko le da duro pelu itumo adani bikose itumo girama. A le pin eyi si ona meta:
   a. Afomo ibere: Eyi ni awon mofiimu ti a fi n kun oro ni ibere. Bi apeere
   a, e, e, i o, o,
   ai, ati, on,oni,
2. Mofiimu Adaduro: Eyi ni mofiimu ti o le da duro pelu itumo kikun. Iru oro bee je odidi oro ti o ko le fo si wewe mo. Bi apeere:
   a. Omo
   b. Ile
   c. Aso
   d. Aja
   e. Iwe
   f. Ise
   g. Oko
   h. Oka

   Ada ab bl.

**ASSIGNMENT**

Pin awon oro wonyi si mofiimu adaduro ati mofiimu afarahe:

1. Onisuga______________________________
2. Alaga ________________________________
3. Adekunle _____________________________
4. Ode __________________________________
5. Akekoo _______________________________

**OSE KEFA**

**Ọ̀nà Tí A Ń Gbà Ṣẹ̀dá**

Orisiirisii ona ni a n gba seda oro ninu ede Yoruba.

1. A le seda oro nipa lilo afomo ibere pelu oro-ise.

| Afomo Ibere | Oro-ise | Oro ti a seda |
|---|---|---|
| A | De | Ade |
| O | De | Ode |
| A | Yo | Ayo |

| | | |
|---|---|---|
| On | ka | onka |
| Oni | Igi | Onigi |

2. A le seda oro nipa lilo oro-ise pelu oro-oruko

| Oro-ise | Oro-oruko | Oro ti a seda |
|---|---|---|
| Je | Oba | Joba |
| Ke | Igbe | Kigbe |
| Ta | Oja | Taja |

3. A le seda oro nipa afomo aarin pomo oro-oruko: ile ki ile = ilekile
4. A le seda oro-oruko nipa apetunpe oro-oruko odun + odun = odoodun
5. A le seda oro nipa apetunpe oro ise. Pana + pana = panapana

A le seda oro nipa isunki odidi gbolohun. Ade gun oke = Adegoke.

**ASSIGNMENT**

Pin awon oro wonyi si mofiimu:

1. Ololade ________________________________
2. Oluko. ________________________________
3. Akekoo.________________________________
4. Olooto.________________________________
5. Wolewole.________________________________

## OSE KEJE (WEEK 7)
## ISE ABINIBI NILE YORUBA

Ise abinibi ni ise atirandiran awon baba-nla wa.

Orisi Ise Abinibi, Osise ati Ohun Elo Ise Kookan

| 1. Ise Abinibi | Oruko Osise | Ohun Elo Ise Kookan |
|---|---|---|
| 2. Ise Agbe | Agbe | Ada, oko, akoro, agbon abbl. |
| 3. Ise Ode | Ode | Ibon, ofa, oko, takute, roba abbl. |
| 4. Ise Agbede | Alagbede | Ewiri, omo owu, irin in, abbl. |
| 5. Ise Isegun | Onisegun | Ewe ati egbo |
| 6. Ise Ope Kiko | Akope | Aha, akeregbe, eya, igba aake, abbl. |
| 7. Ise Emu Dida | Ademu. | Igba, aake tabi ada |
| 8. Ise Irun Didi | Onidiri | Owu ikorun, ooya tabi iyarun, ipara, adi agbon abbl |
| 9. Ise eja pipa | Apeja | Iwo, igere, awon, opon abbl |
| 10. Ise Awo | Babalawo | Opon-ifa, iroke, ikin, iyerosun, opele abbl. |
| 11. Ise ere gbigbe | Agbegilere | Aake, eya, ada, igi, obe abbl. |
| 12. Ise irun gige | Onigbajamo | Abefele, ooya tabi iyarun, aga, abbl. |

| | | |
|---|---|---|
| 13. Ise aro dida | Alaro | Omi, ikoko, aro, aso abbl |
| 14. Ise ile mimo | Omole | Obe irele, eepe, omi abbl |
| 15. Ise ile kikan | Kanlekanle | Pako, oolu, eso,abbl |

**ASSIGNMENT**

Daruko ise igbalode mewaa ki o si daruko ohun elo ise kookan

**1.** ________________________________________
**2.** ________________________________________
**3.** ________________________________________
**4.** ________________________________________
**5.** ________________________________________
**6.** ________________________________________
**7.** ________________________________________
**8.** ________________________________________
**9.** ________________________________________
**10.** ______________________________________

## OSE KEJE

## ETO EKOSE NILE YORUBA

Ni aye atijo, ojo keta ti awon Yoruba ba bi omo ni won yoo ti wo akosejaye omo naa. Ninu akosejaye tabi esentaye yii ni won yoo ti mo iru ise ti omo yoo se bi o ba dagba. Bi omo bat i dagba ti o to oju bon i won yoo ti fi I si odo oga ti yoo ma koi se naa ni odo re. Omo ekose le gbe odo oga tabi awon obi re. Eyi wan i ibamu pelu adehun ti won ba se. bi o ba je ile oga ni omo n gbe ibe ni yoo wa titi yoo fi mo ise. Gbogbo ise ti oga re ba ran an ni o gbodo je. O si tun gbodo maa ran iyawo oga re lowo. Omo ekose le lo odun meta, odun merin, odun marun-un tabi ju bee lo lodo oga re. Eyi wa ni ibamu pelu bi omo naa ba se tete mo ise si.

Bi omo bat i koi se pari ti o si mo ise daradara ni yoo ti gba iyonda lenu ise. Inawo ranpe a maa waye bi omo ekose ba gba iyonda. Bi omo ekose bat i gba iyonda, o lee se atipo lodo oga re titi igba ti yoo fi le da duro. Leyin eyi lo ku ayeye ominira lenu ise.

### Ayeye Ominira Lenu Ise

Leyin ti omo ekose bat i gba iyonda lowo oga re ni yoo ti maa mura fun ayeye ominira lenu ise. Ki o to se eyi gbogbo awon irin ise re gbodo tip e. Ojo ayo ati idunnu ni fun omo to n se ayeye ominira lenu ise pelu awon obi re. Ojo jije ati mimu ni.

Ni idaji kutukutu ni yoo ti gbe ounje lo si odo oga re pelu awon ohun elo igbayonda lenu ise. Yoo lo pelu awon obi ati awon eniyan re. Nigba ti gbogbo eniyan ba ti pejo, okan ninu awon oga ise naa lo maa n dari eto. Yoo maa mu awon ohun elo igbayonda lenu ise ni okookan lati fi se

iwure fun alayeye. Gbogbo awon to peju sibi aseye naa ni yoo mu ohun elo ni okookan lati sure fun omo to kose yege. Leyin eyi ni jije ati mimu yoo bere ni pereu.

### Awon Ohun Elo Igbayonda Lenu Ise

Aadun, oyin, ireke, obi, orogbo, iyo, irin ise kan, epo pupa, ataare, oti ibile, abo iyan kan tabi ju bee lo, oti elerindodo koka kola tabi Fanta, ati bee bee lo.

**ASSIGNMENT**

Salaye ona ti a n gba ko ise lode oni.

______________________________________________________________________
______________________________________________________________________
______________________________________________________________________
______________________________________________________________________
______________________________________________________________________
______________________________________________________________________

## OSE KEJO (WEEK 8)

Asa Igbeyawo Nile Yoruba.

Igbeyawo ni idapo laarin okunrin kan ati obinrin kan lati di took-taya.

Orisii Igbeyawo

1. Igbeyawo ibile.
2. Igbeyawo Soosi.
3. Igbeyawo Mosalasi.
4. **Igbeyawo Kootu / Ile ejo.**

Igbeyawo Ibile: Eyi ni igbeyawo to waye ni liana ibile Yoruba. Agba obinrin kan ninu idile lo maa n dari igbeyawo yii. Igbeyawo ibile fun okunrin laye lati fe iye iyawo ti o ba wu u. Aaye wa fun ikosile ninu igbeyawo ibile. Ni ile baba iyawo ni igbeyawo yii ti maa n waye. Awon took-taya a maa fun ara won ni oruka ninu igbeyawo ibile.

**Orisii Igbeyawo Ibile.**

1. Igbeyawo nisu-loka.
2. Igbeyawo agbagba.
3. Igbeyawo Asante

**Igbeyawo nisu-loka** ni igbeyawo ti won file pon oti, ti won fi ona ro oka ti won si fi gbogbo agbada dinran. Gbogboeb, ara, ore, ojulumo ati molebi lo maa n pejo si iru igbeyawo yii.

**Igbeyawo agbagba** ni igbeyawo ti awon obi fowo si sugbon ti omobinrin ko gba lati fe omokunrun ti awon obi re fowo si. Agbagba ni won maa n gbe iru omobinrin bee lo si ile oko re

**Igbeyawo Asante** ni igbeyawo ti awon obi ko fowo si sugbon ti o wu omobinrin lati fe okunrin ti o wu u. iru obinrin bee le sa tele oko lo.

ASSIGNMENT

Salaye iyato laarin igbeyawo ibile ati igbeyawo ode oni

1. ______________________________________________
2. ______________________________________________
3. ______________________________________________
4. ______________________________________________

**Igbese Igbeyawo Ibile**

1. Ifojusode: Eyi ni igbese akoko ninu asa igbeyawo ibile. Eyi maa n waye nigba ti okunrin ba fi oju sode lati wa omobinrin ti yoo fi se aya.
2. Iwadii: eyi ma n waye nigba ti idile omokunrin ati idile omobinrin ba se iwadii nipa omo ati idile eni ti omo won fe fe. Won a tun maa se iwadii lowo babalawo lati mo bi ojo iwaju igbeyawo naa yoo se ri.
3. Alarina: Alarina ni agbenuso laarin omokunrin ati omobinrin ti won n fe ara won. Bi omokunrin tabi omobinrin ba ni ise ran si ara won alarina ni won yoo ran ni iru ise bee.
4. Isihun / Ijohen: Eyi maa n waye nigba ti omobinrin  ati awon obi re ba gba lati fi omo won fun omokunrin ki o fi se aya.
5. Itoro: Eyi maa n waye nigba ti awon obi omokunrin ba lo si ilea won omobinrin lati toro omo lowo won fun igbeyawo. Aaro kutukutu ni won maa n se ey. Won yoo gbe agbe emu kan lowo. Awon obi omobinrin ko ni fun won ni esi ni ojo yii won yoo da ojo miiran fun won lati wa gba esi.
6. Idana: Leyin ti adehun bat i wo laarin idile kin-in-ni ati idile keji ni won yoo mu ojo kan fun idana. Ojo yii ni won yoo gba nnka ori iyawo naa. Jije ati mimu maa n waye repete. Idile oko ati idile iyawo maa peju lati se idana omo won. Lati ojo yii ni awon mejeeji ti di took-taya. Sugbon iyawo ko ni lo si ile oko re ni ojo yii.
7. Ipalemo: Eyi ni ki took-taya palemo lati se ayeye igbeyawo. Bi won se n palemo nile oko ni won yoo ma palemo ni ile iyawo. Asiko yii ni omobinrin maa n ko ekun iyawo ni odo iya re.
8. Ayeye Igbeyawo: Ojo yii ni iyawo yoo lo si ile oko re. ale ni iyawo maa n lo si ile oko re laye atijo. Ojo yii naa ni omobinrin maa n fi ekun-iyawo dagbere fun awon obi ati awon molebi re.
9. Ibale: eyi ni ki omobinrin ma ti i ni ibalopo pelu okunrin titi di ojo ti o lo si ile oko. Ojo iyi ati eye ni fun omobinrin ati awon obi re. Pelu orin, ilu ati ijo ni idile oko yoo fi mu ebun ti o joju lo fun obi iyawo won. Sugbon itiju nla ni fun omobinrin ti o ba ti fi okunrin ba ara re je ki o to lo si ile oko.
10. Ikorun: Eyi ni ise akoko ti iyawo gbodo se ni ile oko re. Ojo karun-un ti won ba se igbeyawo ni eyi maa n waye.

**Awon ohun elo igbeyawo**

1. Orogbo tumo si ogbo
2. Obi maa n bi iku ati aarun
3. Ataare tumo si omo pupo
4. Oyin tumo si jgbe aye adun ati oyin.
5. Iyo, aadun ati ireke tumo si igbe aye adun

   Awon ohun elo miiran ni epo pupa, isu, iya ewure nla kan, apo iresi kan, owo ori iyawo, opolopo aso ati bata abbl.

**ASSIGNMENT**

Daruko awon ohun elo igbeyawo ode oni marun-un ti o mo.

1. ________________________________________
2. ________________________________________
3. ________________________________________
4. ________________________________________
5. ________________________________________

## OSE KESAN (WEEK 9)

Owe Ati Akanlo Ede Yoruba

Owe je ijinle oro enu awon agba eyi ti o le ran eniyan lowo lati ni oye kikun nipa oro ti enikan so. Owe ni esin oro, oro ni esin owe. Bi oro ba sonu owe ni a fi i wa a.

**Apeere Owe**

1. Agba ko si ilu baje, bale ile ku ile dahoro.
2. Ba mi na omo ni, ko denu olomo.
3. Agba to jin si koto, ko ara yooku logbon.
4. Ogede dudu ko ya busan, omo buruku ko ya alupa.
5. Owo omode ko to pepe, tagbalagba ko wo akeregbe.

**Abuda Owe**

1. Owe Yoruba maa n ni abala meji.
2. Owe Yoruba maa n ni itumo meji. Itumo erefe ati itumo ijinle.
3. Pipa ni a maa n pa owe nile Yoruba.

**Iwulo Owe.**

1. A le fi owe se ikilo.
   a. A kii fi ikanju la obe gbigbona.
   b. Paro ki o niyi, ete ni mu wa.
   c. A kii korira atokun, ka digbo lu eegun.

2. A le fi owe salaye oro.
    a. Eni sun ni a a ji, a ki i ji apiroro.
    b. Enikan kii gbon to bayii ni n o se nnkan mi.
    c. Aisi owo ni a a tilekun mo oodunrun, kin i irinwo baba igbiwo to se.
3. A le fi owe gba eniyan ni imoran.
    a. Ajeje owo kan , ko gbegba dori.
    b. Owo omode ko to pepe, tagbalagb ko wo keregbe.
4. A le fi owe ba eniyan wi.
    a. Ohun oju wa loju ri afago keyin aparo.
    b. Igbeyin ni dun olokuu ada.

**ASSIGNMENT**

Pa owe mewaa ni ede Yoruba ki o si tumo won.

1. ________________________________________
2. ________________________________________
3. ________________________________________
4. ________________________________________
5. ________________________________________
6. ________________________________________
7. ________________________________________
8. ________________________________________
9. ________________________________________
10. ________________________________________

## AKANLO EDE – IDIOMS

Akanlo ede ni awon oro tabi akojopo oro ti itumo won farasin. Akanlo ede maa n ni itumo erefe ati itumo ijinle.

| Akanlo ede | Itumo erefe | Itumo ijinle |
|---|---|---|
| Teri gbaaso | Fi as obo ori. | Ki eniyan ku |
| Ru igi oyin | Ru igi ti o ni oyin ninu. | Bo sinu wahala. |
| Se ogiri leekanna. | Fi eekanna yin ogiri | Ki eniyan maa tiju. |
| Kan oju abe nikoo. | Ki eniyan fi ikuuku so oju abe | Ki eniyan so otito oro |
| Sangba fo. | Ki igba fo | Ki eniyan ku. |
| Gbgi eleera. | Ki eniyan ru igi ti o ni eera ninu. | Ki eniyan fe iyawo onijangbon. |
| Gungi koja ewe | Ki eniyan gungi koja ibi ti o ye. | Ki eniyan se aseju. |
| Gba ekuru je lowo ebora | Ki eniyan gba ounje lowo ohun ti kii se eniyan. | Ki eniyan ku. |
| | | |

**ASSIGNMENT**

Fi akanlo ede mewaa han ninu gbolohun.

1. ________________________________________________
2. ________________________________________________
3. _________________________________________________
4. _________________________________________________
5. _________________________________________________
6. _________________________________________________
7. __________________________________________________
8. ___________________________________________________
9. ____________________________________________________
10.____________________________________________________